**15.** Ti ẹnikan kò ni wọ̀ ọ ju olori buruku lọ.

لَا يَصْلَىٰهَآ إِلَّا ٱلْأَشْقَى ﴿١٥﴾

**16.** Ẹniti o npe (otitọ) nirọ ti o ṣẹri.

ٱلَّذِى كَذَّبَ وَتَوَلَّىٰ ﴿١٦﴾

**17.** Atipe awọn olupaiya (Ọlọhun), a o gbewọn jinna si i.

وَسَيُجَنَّبُهَا ٱلْأَتْقَى ﴿١٧﴾

**18.** Ẹniti o nfi owó rẹ̀ tọrẹ, lati fi fọ ẹ̀mi rẹ̀ mọ.

ٱلَّذِى يُؤْتِى مَالَهُۥ يَتَزَكَّىٰ ﴿١٨﴾

**19.** Atipe kòsi ẹnikan ti o ni Õre idẹra kan lọdọ rẹ̀ lati fi gba ẹsan.

وَمَا لِأَحَدٍ عِندَهُۥ مِن نِّعْمَةٍ تُجْزَىٰٓ ﴿١٩﴾

**20.** Ayafi lati fi wa ojure Oluwa rẹ̀ ti O ga julọ.

إِلَّا ٱبْتِغَآءَ وَجْهِ رَبِّهِ ٱلْأَعْلَىٰ ﴿٢٠﴾

**21.** Atipe laipẹ yio di ẹniti o nyọnu.

وَلَسَوْفَ يَرْضَىٰ ﴿٢١﴾

## *(93) Suratul - Dhuhã*

سُورَةُ الضُّحَىٰ

*Ni orukọ Ọlọhun Ajọkẹ aiye,*
*Aṣakẹ ọrun.*

بِسْمِ ٱللَّهِ ٱلرَّحْمَٰنِ ٱلرَّحِيمِ

**1.** Mo fi imọlẹ̀ iyalẹta (Dhùhã) bura.

وَٱلضُّحَىٰ ﴿١﴾

**2.** Ati òru nigbati o ba bolẹ̀ biribiri.

وَٱلَّيْلِ إِذَا سَجَىٰ ﴿٢﴾

**3.** Oluwa rẹ kò fi ọ silẹ, kò si binu si ẹ.

مَا وَدَّعَكَ رَبُّكَ وَمَا قَلَىٰ ﴿٣﴾

**4.** Atipe dajudaju igbẹhin (ọrun) yio dara fun ọ ju akọkọ (aye) lọ.

وَلَلْءَاخِرَةُ خَيْرٌ لَّكَ مِنَ ٱلْأُولَىٰ ﴿٤﴾

**5.** Atipe laipẹ Oluwa rẹ yio fun ọ ni ohun ti yio dun mọ ọ ninu.

وَلَسَوْفَ يُعْطِيكَ رَبُّكَ فَتَرْضَىٰٓ ﴿٥﴾

**6.** Nję kò ri ǫ ni ǫmǫ-orukan ti O si dãbo bò ǫ?

أَلَمۡ يَجِدۡكَ يَتِيمٗا فَـَٔاوَىٰ ٦

**7.** Atipe O ri ǫ ni ęniti kò mǫ̀nà O si fi ǫna mǫ̀ ǫ?

وَوَجَدَكَ ضَآلّٗا فَهَدَىٰ ٧

**8.** Atipe O ri ǫ ni alaini O si sǫ ǫ di ęni ti o ni?

وَوَجَدَكَ عَآئِلٗا فَأَغۡنَىٰ ٨

**9.** Nitorina maşe ni ǫmǫ-orukan lara.

فَأَمَّا ٱلۡيَتِيمَ فَلَا تَقۡهَرۡ ٩

**10.** Atipe ki o maşe kanra mǫ alagbe.

وَأَمَّا ٱلسَّآئِلَ فَلَا تَنۡهَرۡ ١٠

**11.** Atipe õre idęra Oluwa rę, sǫ ǫ jade.

وَأَمَّا بِنِعۡمَةِ رَبِّكَ فَحَدِّثۡ ١١

## *(94) Suratul - Şarhi*

سُورَةُ الشَّرۡحِ

*Ni orukǫ Qlǫhun Ajǫkę aiye, Aşakę ǫrun.*

بِسۡمِ ٱللَّهِ ٱلرَّحۡمَٰنِ ٱلرَّحِيمِ

**1.** Nję Awa kò ti şipaya igbaiya rę fun ǫ bi?

أَلَمۡ نَشۡرَحۡ لَكَ صَدۡرَكَ ١

**2.** Atipe Awa ti gbe ęru wiwuwo rę kuro fun ǫ.

وَوَضَعۡنَا عَنكَ وِزۡرَكَ ٢

**3.** Eyiti o wǫ̀ ǫ lǫrùn.

ٱلَّذِيٓ أَنقَضَ ظَهۡرَكَ ٣

**4.** A si ti gbe iranti orukǫ rę ga fun ǫ.

وَرَفَعۡنَا لَكَ ذِكۡرَكَ ٤

**5.** Dajudaju lęhin inira irǫrun mbę.

فَإِنَّ مَعَ ٱلۡعُسۡرِ يُسۡرًا ٥

**6.** Dajudaju lęhin inira irǫrun mbę.

إِنَّ مَعَ ٱلۡعُسۡرِ يُسۡرًا ٦